# ASE BẸLṢASSARI

## Daniẹli 5:1-31

## ẸKỌ 422 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "A ti wọ̀n ọ wò ninu òṣuwọn, iwọ kò si to" (Daniẹli 5:27).**

**I A Sọ Awọn Ohun-Elo Mimọ́ Oluwa Di Eeri**

1 Bẹlṣassari ti ọti n pa paṣẹ pe ki a lo awọn ohun-elo mimọ́ naa, Daniẹli 5:1-3; 2 Kronika 36:7

2 A sọ awọn ohun-elo naa di alaiyẹ nipa fifi wọn mu ọti waini ti a fi rubọ si oriṣa, Daniẹli 5:4

**II Ọwọ́ lara Ogiri**

1 Ohun ti a kọ sara ogiri daamu ọba, Daniẹli 5:5, 6

2 Awọn ọlọgbọ́n Babeli kuna, Daniẹli 5:7-9; Isaiah 44:25

**III Itumọ ti Daniẹli Ṣe ati Ikú Bẹlṣassari**

1 Ayaba ranti Daniẹli, Daniẹli 5:10-12

2 A mú Daniẹli wá siwaju ọba, Daniẹli 5:13-16

3 Daniẹli bá ọba wi, Daniẹli 5:17-24

4 Daniẹli tumọ iwe ti a kọ naa, Daniẹli 5:25-28

5 A gbé Daniẹli ga, a pa Bẹlṣassari, Dariusi si jọba, Daniẹli 5:29-31

ALAYE

**Awọn Iwe**

Bi ọjọ́ kan ti n kọja lọ, a kò le pe e pada mọ́. Gbogbo akọsilẹ rẹ̀ ti kọja lọ si ayeraye. Johannu sọ fun wa ninu Iwe Ifihan pe, Ọlọrun fun oun ni iṣipaya wakati ti Ọlọrun yoo joko ni itẹ idajọ. Gbogbo ayé pe jọ pọ̀ niwaju Rẹ̀. Ikú ati ipo-oku mu oku ti o wà ninu wọn jade ki wọn ki o ba le fara hàn ni Ibi Idajọ nla lati gba idajọ ti o tọ́. Johannu wi pe a ṣi awọn iwé. Ninu wọn ni akọsilẹ igbesi-ayé awọn eniyan wà. Nipa akọsilẹ wọnyii ni a o ti ṣe idajọ gbogbo eniyan.

Ninu ori karun-un Iwe Daniẹli ni itan ọkunrin kan wà ti o gbé ọkàn rẹ̀ ga si Ọlọrun alaaye - Ọlọrun ti o ti wà, ti yoo si wà, ti o mọ opin lati ibẹrẹ, ti o mọ ero ìkọkọ ọkàn wá lati ọ̀na jijin, ohun gbogbo ni o wà ni ihoho ti o si ṣipaya niwaju Ẹni ti a ni ba lò. Onipsalmu wi bayii pe: "Nibo li emi o gbe lọ kuro lọwọ ẹmi rẹ? tabi nibo li emi o sárè kuro niwaju rẹ?" Oju kan wà ti O n ṣọ́ wa, ni Ọrun ni akọsilẹ olukuluku wa si wà.

**Babiloni**

Bẹlṣassari jẹ́ alakoso gbogbo ijọba agbaye. Iwe itan sọ fun wa pe ijọba Kaldea tan ká gbogbo ayé igba nì. Nigba ti Bẹlṣassari de ori oyè, Babiloni ti dé gongo ninu ogo rẹ̀. Ṣugbọn bi giga ijọba naa ti pọ to nì, Ọlọrun wi pe, Babiloni nla yoo wo lulẹ.

"Ododo ni igbé orilẹ-ède leke; ṣugbọn ẹ̀ṣẹ li ẹ̀gan orilẹ-ède".

**Igbẹkẹle Bẹlṣassari**

Bẹlṣassari ọba se ase nla alarinrin ni olu-ilu ijọba Babiloni. O pe ẹgbẹrun awọn ijoye rẹ̀, o si n mu ọti waini niwaju wọn. O mọ̀ pe awọn ọmọ-ogun Mẹdia ati Perṣia wà lẹyin odi ilu. Pe ogun ọta le kọlu ogiri ti o yi ilu rẹ̀ ká jẹ́ ọ̀rọ asán ati ẹ̀gan niwaju rẹ̀.

Lai si aniani Bẹlṣassari ati awọn ijoye rẹ̀ lero pe kò sewu lalẹ ọjọ naa. Awọn ni n ṣe ijọba lori Babiloni, ilu nla ati ologo ti o dé gongo okiki ati ọla ti kò si ilu miiran ti o ti i dé ri. Gẹgẹ bi akọsilẹ iwe itan, ogiri ti o yi Babiloni ká jẹ́ ọdunrun ẹsẹ̀ ni giga o si fẹ ni ọgọrin ẹsẹ̀; awọn ọmọ-ogun wà yi i ká, o si

hàn gbangba pe eto ijọba rẹ̀ dara; ṣugbọn kò si ogiri bi o ti le wu ki o ga to, tabi ki o nipọn to, tabi ijọba bi o ti le lagbara to, bi Ọlọrun ba dide si i, yoo mi ogiri rẹ̀, yoo si fọ́ ijọba naa.

"Nitoriti a kò mu idajọ ṣẹ kánkán si iṣẹ buburu, nitorina aiya awọn ọmọ enia mura pãpa lati huwa ibi" (Oniwasu 8:11).

**Awọn ti o Kọ Ọlọrun Silẹ**

Ounjẹ adidun, ọla ati iyẹsi ti a n ṣe fun Bẹlṣasaari ni ibi ase yii kò tẹ ẹ lọrun. O fẹ fi hàn fun awọn eniyan pe oun kò ni igbagbọ́ ninu Ọlọrun Israẹli. Ohun kan naa yii ni pupọ n ṣe lode oni. Wọn n ṣe "féfé," wọn si n kọ Ọlọrun ati igbagbọ́ ayebaye. Lọjọ oni awọn oniwaasu miiran tilẹ n wi pe Jesu ki i ṣe Ọmọ Ọlọrun.

Ni alẹ ọjọ naa, Bẹlṣassari fẹ́ gbé ara rẹ̀ ga si Ọlọrun mimọ́, o si ṣe e si iparun ati idalẹbi ara rẹ̀. Ase nla alariwo ni eyi; ṣugbọn Ọlọrun gba a laye titi o fi gbé ẹsẹ kan jinna siwaju si i ni ọna ẹ̀ṣẹ.

O ranti aago wura ati ti fadaka mimọ́ ti baba rẹ̀ Nebukadnessari ti kó lati Tẹmpili Jerusalẹmu wá. O ranṣẹ pe ki a kó wọn wá, wọn si fi ọti waini kún wọn de eti fun awọn ijòye rẹ̀ ati awọn aya wọn; wọn si n fi aago mimọ́ Ọlọrun mu waini. Wọn n yin oriṣa wura ati fadaka, oriṣa igi ati okuta – gbogbo awọn oriṣa ṣugbọn ki i ṣe Ọlọrun tootọ.

**Iwe Ti A Kọ**

Ni wakati kan naa ni awọn ika ọwọ́ eniyan hàn lara ogiri niwaju ọpa fitila. Ọwọ́ naa n kọwe. Oju ọba yipada; eekunsẹ rẹ̀ mejeeji si n lu ara wọn. O ranṣẹ pe awọn alafọṣẹ ati awọn aworawọ̀, awọn ọlọgbọ́n Kaldea, ki wọn wá ka ohun ti a kọ naa; ṣugbọn kò si ẹni kan ninu wọn ti o le tumọ ohun ti ika Ọlọrun kọ sara ogiri naa.

Bi o ba ṣe pe iwe ti a kọ sara ogiri ti o n ṣe nipa iparun Bẹlṣassri le daamu rẹ̀ to bẹẹ, bawo ni yoo ti ri lati duro niwaju Itẹ Idajọ Ọlọrun nibi ti a o ti ṣe iṣipaya igbesi-ayé olukuluku? Ọ̀kan ninu awọn ti o kọ Bibeli rán wa leti pe: "Ninu ohunkohun ti ọkàn wa ba ndá wa lẹbi, nitoripe Ọlọrun tobi jù ọkàn wa lọ." Oun yoo dá wa lẹbi ju eyi ti ọkàn wa le dá wa lẹbi lọ fun iṣẹ buburu. Yoo ti buru to lati dojukọ iṣipaya igbesi-ayé ẹ̀ṣẹ niwaju Itẹ Idajọ!

Nikẹyin, nitori igbe, iwariri ati rudurudu ti o n ṣẹlẹ, ayaba wọ ile-ase naa wá. O wi pe ẹni kan wà ni ijọba Bẹlṣassari ninu ẹni ti Ẹmi Ọlọrun mimọ́ gbé wà ati ni igba ayé Nebukadanessari oun ni o ṣe itumọ ọ̀rọ ti o diju. Bi a ba pe Daniẹli oun le tumọ ohun ti a kọ sara ogiri naa. Daniẹli wá si ibi ase naa, o si wi fun ọba pe: "Iwọ ọba, Ọlọrun Ọga-ogo fi ijọba, ati ọlanla, ati ogo, ati ọlá fun Nebukadnessari, baba rẹ … Ṣugbọn nigbati ọkàn rẹ̀ gbega, ti inu rẹ̀ si le nipa igberaga, a mu u kuro lori itẹ rẹ̀, nwọn si gba ogo rẹ̀ lọwọ rẹ̀ … Ati iwọ Bẹlṣassari, ọmọ rẹ̀, iwọ kò rẹ̀ ọkàn rẹ silẹ, bi iwọ si tilẹ ti mọ̀ gbogbo nkan wọnyi" (Daniẹli 5:18-22). Wo bi òye ti kù fun eniyan tó lati kọ́ ẹ̀kọ́ nipa bi Ọlọrun ti n bá wọn lò tabi lati fi iriri ti awọn ẹlomiran ṣe arikọgbọn! O dabi ẹni pe olukuluku eniyan ni o ni lati kọ́ ẹ̀kọ́ naa fun ara rẹ̀. Iyà ẹ̀ṣẹ ti ẹlomiran jẹ lati ọwọ́ Ọlọrun kò to fun un lati fi kọ́ ẹ̀kọ́.

"Ọmọ, ranti" ni awọn ọrọ ti Abrahamu sọ si ọlọrọ nì ti o wà ninu ìṣẹ́ oró. Bi awọn eniyan ba le kọ́ ẹ̀kọ́ lati inu iwe itan, atubọtan ayé wọn yoo ti ni iyatọ to!

**A Wọ̀n ọ́n, Kò si Tó**

Daniẹli ka ohun ti a kọ naa, o si tumọ rẹ̀. O sọ fun ọba pe a o gba ijọba naa kuro lọwọ rẹ̀, a o si fi i fun awọn Mẹdia ati Perṣia. Si Bẹlṣassari ni o sọ awọn ọrọ wọnyi, "A ti wọ̀n ọ wò ninu òṣuwọn, iwọ kò si to." Awọn opitan sọ fun wa pe awọn ara Mẹdia yí ipa odo Eufrate pada, wọn si bá ipa ọna odo naa wọle labẹ ogiri. Wọn dá awọn iṣọ́ niji, wọn mú awọn ọmọ-ogun, wọn wọle, wọn si pa ilu naa run. Bẹlṣassari fẹrẹ má ti gbọ́ idajọ rẹ̀ ni ẹnu Daniẹli tán nigba ti igbe ta soke pe awọn ara Mẹdia ati Perṣia ti wọ ilu. Ni alẹ ọjọ naa ẹmi ọba buburu naa lọ sọdọ Ọlọrun lati gba idajọ gbigbona Ọlọrun Ẹni ti o ti kẹgan.

Bibeli sọ fun wa pe: "Ki a máṣe tàn nyin jẹ: a kò le gàn Ọlọrun: nitori ohunkohun ti enia ba funrugbin, on ni yio si ká." A n ṣe akọsilẹ igbesi-ayé wa. Nigba ti Ẹni Laelae nì ti a wọ laṣọ igbẹsan

ayeraye yoo joko lori Itẹ Rẹ̀, awọn ẹlẹṣẹ yoo fi oju kan oju ti o n rẹ̀ dòdò bi iná, wọn yoo si jiyin bi wọn ti ṣe lo igbesi-ayé wọn nihin.

Ki ni ṣẹlẹ si ilu Babiloni? Lọjọ oni o jẹ́ ibugbe fun ekute ati àdán. Awọn okiti nihin tabi lọhun ni o kù silẹ ninu ile nla nì. Ijọba Kaldea kọja lọ. Kò si bi ijọba kan ti le lagbara to: o le ni ọkọ ogun ninu agbami okun ati ọpọlọpọ ologun: ṣugbọn nigba ti Ọlọrun bá paṣẹ ègbé si i lori, yoo ṣubu dandan ni.

**Ayeraye**

A n sun mọ́ ibugbe wa ayeraye – i baa ṣe pẹlu imurasilẹ tabi aimurasilẹ, i baa ṣe ọ̀na ootọ tabi èké. Bi o ba jẹ ẹni ti a kò ti i gbala, tabi bi o ba jẹ afasẹyin, bi ohun kan ba ti gba iṣẹgun rẹ, iwọ o ba Ọlọrun pade pẹlu ọkàn idalẹbi. Bi ohun kan ba ti wọ inu ọkàn rẹ, ti gbòngbo ikorò bá si wà nibẹ, ranti pe yoo duro de ọ ni ayeraye. O le jẹ pe o ti mu "gbòngbo ikorò" naa lọ si ile Ọlọrun, o si ti mu un pada si ile, ṣugbọn gbogbo eto isin ti iwọ ti ṣe ki yoo mu alaafia bá ọkan rẹ titi agbara ti o wà ninu Ẹjẹ ti Kalfari yoo fi mu un kuro nipa iṣẹ́ Ẹmi Mimọ́ Ọlọrun.

"Wọ̀n ọ wò ninu oṣuwọn, iwọ kò si to" - lilọ si ayeraye nibi ti kò si kika ọjọ́, kò si agogo ti a fi kọ́ sara ogiri. Wo bi ipin awọn wọnni ti o lọ sinu òkunkun biribiri nibi ègbé ti buru to! Ẹgbẹẹgbẹrun ọna ẹgbẹrun ọdun kò le mu wọn sun mọ́ opin ijiya wọn. "Mura lati pade Ọlọrun rẹ."

AWỌN IBEERE

1 Igba meloo ni a pe Daniẹli lati ṣe itumọ àlá?
2 Ṣe apejuwe ase Bẹlṣassari.
3 Ki ni ṣẹlẹ si ọba nigba ti o ri ọwọ́ lara ogiri?
4 Ta ni sọ fun ọba nipa Daniẹli?
5 Ki ni Daniẹli mú wá si iranti ọba?
6 Ki ni Daniẹli sọ fun ọba pe o jẹbi rẹ̀?
7 Ki ni Ọlọrun kọ sara ogiri?
8 Nigba wo ni a pa Bẹlṣassari?
9 Ta ni gba ijọba naa?
10 Ẹkọ wo ni a ri kọ́ ninu ohun ti o ṣẹlẹ si ọba yii?